**ÀDÚRÀ LÁTI DÁ WỌN DÚRÓ KÍ WỌ́N TÓ DÁ Ọ DÚRÓ (APÁ KẸTA)**

**Bíbélì Kíkà: Ẹ́stérì 7 / Ìjẹ́wọ́: Deut. 33:27**

1. Agbárakágbára nínú ìdílé mi tí wọ́n yàn láti gé ayé mi kúrú, kú dípò mi, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo pánpẹ́ ikú àìtọ́jọ́ tí ọ̀tá ṣètò lòdì sí mi yóò mú ẹni tó ni í, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogob ibojì sátánì tí wọ́n gbẹ́ fún mi, gbé ẹni tó gbẹ́ ọ mìn, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ohun-ìjà ikú tí ọ̀tá rán sínú ayé mi láti pamírun, tapadà, kí o sì pa ẹni tó rán ọ́ run, ní orúkọ Jésù.
5. Ẹ̀dá ìyówù tó n wá mi láti pa, pa ara rẹ run, ní orúkọ Jésù.
6. Rìkíṣí òkùnkùn tí wọ́n yàn láti gé ayé mi kúrú, tapadà, ní orúkọ Jésù.
7. Ọjọ́ tí wọ́n dá láti pamírun yóò di ọjọ́ ọlá mi, ní orúkọ Jésù.
8. Olúwa, jẹ́ kí àgọ́ ara Hámánì di gbígbésin sínú ibojì tí ó ṣètò lòdì sí mi, ní orúkọ Jésù.
9. Ọwọ́ Nlá Ọlọ́run, mú mi jáde kúrò nínú kòtò ikú tí ọ̀tá jù mí sí, jẹ́ kí wọ́n ṣubú sínú rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí ọwọ́ ọ̀tún Rẹ ṣàwárí gbogbo àwọn ọ̀tá mi, jẹ́ kí ọwọ́ Rẹ ṣe ìparun fún gbogbo àwọn tó n fẹ́ kí n kú, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, mú ikú àti ẹ̀rù ikú kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
12. Kìnìún ẹ̀yà Júdà, jó gbogbo ẹ̀dá ìkà tí wọ́n rán níṣẹ́ láti jẹmírun, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, ní ọjọ́ tí wọ́n ti yàn kí ìdílé mi ṣọ̀fọ̀, sọ ọ́ di ọjọ́ ijó, ìyìn àti ìdúpẹ́, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo àdéhùn pẹ̀lú ikú nínú ìdílé mi yóò yípadà lójúẹsẹ̀ di ìjákulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
15. Mo dá padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, àlákàlá tí yóò fa ikú, ní orúkọ Jésù.
16. Èmi kòní sun oorun ikú àìtọ́jọ́, ní orúkọ Jésù.
17. Ọkùnrin alágbára ikú tí wọ́n yàn láti pa mí ṣíwájú ọjọ́ mi, kílo ṣì n ṣe láyé? kú, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo olùkan-pósí tí wọ́n yàn láti kan pósí fún mi, kú dípò mi, ní orúkọ Jésù.
19. Mo pàṣẹ ikú àìtọ́jọ́ sórí ẹnikẹ́ni tó n fẹ́ kí n kú ikú àìtọ́jọ́, ní orúkọ Jésù.

20. Agbára òkùnkùn ìyówù tó rìn ìhòhò láti gégùn ikú fún mi, wólulẹ̀, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo gúnugún òkùnkùn tí ó n farahàn lójú àlá mi, pa ara rẹ run, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.